# ỌJỌ́ ÈTÙTÙ

## Lefitiku 16:1-34; 23:26:-32

## ẸKỌ 86 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "OLUWA si ti mu aiṣedede wa gbogbo pade lara rẹ̀" (Isaiah 53:6).**

**Igbala Nipasẹ Ẹjẹ Naa**

Ọna kan ṣoṣo ló wà nipa eyi ti eniyan fi le ri igbala kuro ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀: nipasẹ Ẹjẹ Jesu. Jesu wi pe: "Nitori eyi li ẹ̀jẹ mi ti majẹmu titun, ti a ta silẹ fun ọ̀pọ enia fun imukuro ẹ̀ṣẹ" (Matteu 26:28).

Nigba ti Oluwa wa wà laye O gbé igbesi-ayé ti o lẹwà, O si kọ́ awọn eniyan bi wọn ṣe ni lati maa gbé bi wọn ba n fẹ lọ si Ọrun. Ṣugbọn kò si eniyan ti o le gbọran si ẹkọ Rẹ̀ ayafi bi a ba ti dari ẹ̀ṣẹ rẹ̀ jì, ti a ba si ti fi Ẹjẹ Olugbala wẹ̀ ẹ́ nù. Bẹẹ ni a ni lati gbọran si gbogbo ẹkọ wọnni, bi bẹẹ kọ́ a ki yoo le wọ Ọrun. "Bi iwọ ba n fẹ wọ̀ ibi iye, pa ofin mọ́" (Matteu 19:17).

Ki Jesu to lọ si Ọrun O sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe, "Ninu ile baba mi ọ̀pọlọpọ ibugbe li o wà: ibamáṣe bẽ, emi iba ti sọ fun nyin. Nitori emi nlọ ipèse àye silẹ fun nyin" (Johannu 14:2). Sa woye awọn ibi ti o lẹwa ti o ti ri ninu ayé, ki o si ranti pé Jesu ti sọ pé Ọ̀run lẹ́wà ju ohunkohun ti a le ronu rẹ̀ ninu ayé yii. Gbogbo wa ni a fẹ lọ si Ọrun lati maa gbé ibi ologo ni titi lae.

**Awọn Eniyan Mimọ́ fun Ibugbe Mimọ́**

Ṣugbọn bi Ọrun ba jẹ́ ibi iyanu to bẹẹ, Ọlọrun kò ni jẹ ki awọn ẹlẹṣẹ gbé ibẹ̀. Olukuluku ẹni ti yoo ba lọ si Ọrun yoo jẹ́ eniyan mimọ́, ti a ti fi Ẹjẹ Jesu wẹ̀ mọ́. Nigba ti Johannu Ayanfẹ wà ni Erekuṣu Patmo, ẹni ti wọn lé kuro ni ile rẹ̀ nitori awọn eniyan buburu kò fẹ ki o waasu Jesu, o rí iran kan. O ri ọpọlọpọ eniyan ninu aṣọ funfun, pẹlu imọ ọpẹ ni ọwọ wọn, wọn n kọrin yí Itẹ Ọlọrun ká. Johannu n beere pe ta ni awọn wọnyii? Ọkan ninu awọn eniyan mimọ́ ni Ọrun wi fun Johannu pe, "Awọn wọnyi li o jade lati inu ipọnju nla, nwọn si fọ̀ aṣọ wọn, nwọn si sọ wọn di funfun ninu ẹ̀jẹ Ọdọ-Agutan na" (Ifihan 7:14). Wọn ti ri igbala nipasẹ Ẹjẹ Jesu; nitori idi eyi ni aṣọ wọn ṣe funfun ti wọ́n si fi le kọrin iyin si Ọlọrun ni Ọrun.

**Ominira ti Ẹmi**

Tita ti Jesu ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ fun ẹ̀ṣẹ awọn eniyan ni a n pè ni Etutu. Nipasẹ Etutu naa ni a fi n dari awọn ẹ̀ṣẹ wa jì wá ti a si n pa wọn rẹ́ laelae. Nigba ti a o ba duro niwaju Ọlọrun lati jihin bi a ti lo igbesi-ayé wa, a kò ni jẹbi awọn ẹ̀ṣẹ ti a ti dá tẹlẹ bi a ba ti bẹ Jesu pe ki O dariji ki O si wẹ̀ wọ́n nù.

O dabi ẹni pe kò yé awọn kan pe n ṣe ni Jesu kú lati ṣetutu fun ẹ̀ṣẹ wa. Wọn ṣe bi iṣẹ Rẹ̀ laye já si asán nitori Oun kò gbé ijọba Rẹ̀ kalẹ ninu ayé gẹgẹ bi awọn eniyan igba naa ti ro pe yoo ṣe. Awọn Ọmọ Israẹli (eyi ni awọn Ju) wà ni isinru awọn ara Romu nigba ti Jesu wà layé, wọn si n ṣafẹri Messia kan ti yoo wa jẹ Ọba wọn ti yoo si doju ijọba Romu bolẹ. Ṣugbọn eyi kọ́ ni Jesu wá fún. O wá lati ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ lati wẹ ẹ̀ṣẹ araye nù. O ṣanfaani lati bọ́ lọwọ ẹ̀ṣẹ ati lati mura silẹ lati lọ si Ọrun ju lati gbé ni ilẹ ominira ninu ayé yii lọ.

**Ohun Nla ti Irapada Gba**

Ṣiro ohun ti o gba Jesu lati rà wá pada kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa! Oun kò sáà ṣe ibi kankan ri; O wà pẹlu Ọlọrun nigba ti a dá awọn ayé, "lẹhin rẹ̀ a ko si da ohun kan ninu ohun ti a da" (Johannu 1:3). Sibẹ, O ṣetan lati fi ibugbe Rẹ́ daradara silẹ ni Ọrun ati lati wá sinu ayé ni iri eniyan, ki O wá ki O si jiya gẹgẹ bi awa (ṣugbọn lai si ẹ̀ṣẹ) ati lati san owo irapada wa nipa fifi ẹmi Rẹ̀ lelẹ fun ikú oro ori agbelebu. "Ṣugbọn a ṣá a li ọgbẹ nitori irekọja wa, a pa a li ara nitori aiṣedede wa; ìna alafia wa wà lara rẹ, ati nipa ìna rẹ̀ li a fi mu wa lara da" (Isaiah 53:5). A ri ninu ẹsẹ yii pe ileri iwosan tun wà ninu Etutu naa. Peteru tun sọ ileri yii nigba ti o wi pe: "Ẹniti on tikararẹ̀ fi ara rẹ̀ rù ẹ̀ṣẹ wa lori igi, pe ki awa ki o le di okú si ẹ̀ṣẹ ki a si di ãye si ododo: nipa ìnà ẹniti a mu nyin larada" (1 Peteru 2:24).

**Ọjọ Etutu Awọn Ọmọ Israẹli**

Ọlọrun fẹ fi han awọn Ọmọ Israẹli bi ọrọ nipa Etutu yii ti ṣe danindanin to, nitori bẹẹ O yan ọjọ kan ninu ọdun kọọkan ninu eyi ti wọn n ṣe irubọ, eyi ti o n ṣe apẹẹrẹ iṣẹ ti Jesu yoo ṣe nipa fi fi ẹmi ti Rẹ̀ ṣe ẹbọ aayè. Awọn eniyan naa n ta ẹjẹ ẹran silẹ ninu irubọ wọn ojoojumọ, gbogbo rẹ̀ si jẹ apẹẹrẹ, lọna kan tabi omiran, ohun ti Jesu yoo tipa Ẹjẹ Rẹ̀ ti yoo ta silẹ ṣe. Ṣugbọn ni Ọjọ Etutu awọn irubọ pataki kan wà ti wọn fi hàn kedere ju bẹẹ lọ, ipá tabi agbara ti Ẹjẹ Jesu yoo ní. Awọn irubọ wọnyii wà fun gbogbo orilẹ-ède naa patapata, lati fihàn pé "ẹnikẹni ti o ba fẹ" ni ó lè rí igbala. Ṣugbọn fun ẹ̀ṣẹ wọn bi ẹni kọọkan, awọn eniyan naa ṣi ni lati mu ẹbọ irekọja wọn wá sibẹ. Bẹẹ naa ni, a kò le ri igbala nipa ileri Kristi pe gbogbo agbaye ni a le gbà là, ayafi bi a ba wá ni kọọkan pẹlu ironupiwada ti a si bẹ Jesu pe ki o dari ẹ̀ṣẹ wa ji wa. "Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ainipẹkun" (Johannu 3:16).

Ọjọ Etutu naa jẹ ọjọ ironu ninu eyi ti awọn Ọmọ Israẹli ni lati ranti ẹ̀ṣẹ wọn. O ni lati yé wọn pe ayọ̀ tootọ kò si titi a o fi mú ẹ̀ṣẹ wọn lọ. A kò le ni ayọ̀ tootọ titi a o fi tipasẹ Ẹjẹ Jesu wẹ ẹ̀ṣẹ wa nù kuro.

**Olori Alufaa Nikan**

A ti kọ́ ẹkọ́ nipa gẹgẹ bi Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀ ọkunrin ti jẹ́ alufaa, ṣugbọn Aarọni ni olori alufaa. Oun nikan ni o n ṣe iṣẹ-isin ni Ọjọ Etutu, gẹgẹ bi Jesu, Olori Alufaa wa, ti dá nikan ṣe Etutu fun wa. Oun, "lẹhin ti o ti ṣe iwẹnu ẹ̀ṣẹ, o joko li ọwọ́ ọtún Ọlánla li oke" (Heberu 1:3). Aarọni ṣọra gidigidi lati ṣe ohun gbogbo kinnikinni gẹgẹ

bi Ọlọrun ti pa a laṣẹ.  Aṣọ pataki ni o n wọ̀ ni ọjọ yii, o si n wẹ ara rẹ̀ nigba pupọ lati ri i daju pe oun jẹ́ mimọ́, apẹẹrẹ wiwà ni mimọ́.

**Ọna Ibi Mimọ́ Julọ**

Ko si eniyan ti o le wọ Ibi Mimọ́ Julọ bikoṣe olori alufaa, ni Ọjọ Etutu nikan ni oun si le wọ ibẹ̀.  Wo ohun ti o jẹ́ fun un lati gbé aṣọ ikele soke ati lati duro niwaju Ifarahan Ọlọrun eyi ti o wà lori Itẹ-Aanu.  Aarọni mu ẹyin iná sinu awo turari wura rẹ̀ ati turari lati sun, eyi ti yoo ṣe eefin ti yoo jẹ́ ikuuku laaarin oun ati Ọlọrun, “ki o má ba kú” O ni lati tọ Ọlọrun wá pẹlu iṣọra ati ọ̀wọ̀.  Ọlọrun n fẹ ki a wá siwaju Oun pẹlu ironu, ki oye iwa mimọ́ Rẹ̀ ki o yé ni.  A ni lati fi ọ̀wọ̀ fun Ile Ọlọrun, ki a si huwa bi ẹni pe a mọ̀ pe Jesu n ṣọ́ wa ni iṣẹju gbogbo.  Nigba ti a ba n gbadura a ni lati mọ̀ pe Ẹlẹda wa ni a n ba sọrọ, Ẹni ti o dá awọn ọrun ati ayé ati ohun gbogbo ti o wà ninu wọn pẹlu.  Sa ro ohun ti o jẹ lati le gbadura si Ọlọrun Mimọ́ ati Iyanu bayii, ki O si dahun adura wa!

Wọn maa n ṣe irubọ pataki kan pẹlu ewurẹ meji ni Ọjọ Etutu.  Aarọni a pa ọkan a si mú ẹjẹ rẹ̀ wọ Ibi Mimọ́ Julọ lati fi wọ́n Itẹ- Aanu fun awọn eniyan naa.  Awọn Ọmọ Israẹli kò le wọle funra wọn, ṣugbọn Aarọni a maa ṣe irubọ naa fun wọn.

Wo iru aibalẹ ọkàn ti wọn fi n reti ipadabọ Aarọni!  Wọn a duro lode wọn a si maa gbadura nigba ti oun ba n wọ́n ẹjẹ naa ninu Ibi Mimọ́ Julọ.  Awọn alufaa iyoku kò tilẹ le wà ninu Ibi Mimọ nibi ti pẹpẹ wura ati ọpa fitila wura wà nigba ti Aarọni ba wà ni Ibi Mimọ́ Julọ.  Agogo wa yika eti aṣọ Aarọni, eyi a si maa dún bi o ti n rin kiri, a si maa jẹ ki awọn eniyan ti n feti silẹ lode mọ̀ pe o wà laaye sibẹ ati pe o n ṣe etutu fun wọn.

**Aṣọ Ikele Ya**

Nigba ti Jesu kú lori agbelebu aṣọ ikele Tẹmpili faya, ki olukuluku eniyan ba le wọ inu Ibi Mimọ́ Julọ.  Itumọ eyi ni pe nisisiyii gbogbo wa le lọ siwaju Itẹ-Aanu funra wa a kò si wá alufaa ti ayé kankan lati ṣe alagbawi fun wa niwaju Ọlọrun mọ́.  Nigba ti Jesu pari iṣẹ irapada ti O si lọ si Ọrun lati jẹ́ Olori Alufaa wa ni Ibi Mimọ́ Julọ ni Ọrun, a kò tun fẹ́ alufaa tabi ijọsin inu agọ mọ.

**Olori Alufaa Wa**

Jesu kò lọ si Ọrun pẹlu ẹjẹ akọ maluu ati ti ewurẹ, bi Aarọni ti i lọ sinu Ibi Mimọ́ Julọ, ṣugbọn O yọọda Ẹjẹ ti Rẹ̀.  A gún ọwọ ati ẹsẹ ati iha Rẹ̀ nigba ti a kan An mọgi, a si ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ lati ṣetutu fun ẹ̀ṣẹ wa.  Lẹyin ti O ti san gbese ti o ṣe iyebiye to bẹẹ, iwọ ha rò pe a le gba ọna miiran de Ọrun yatọ si eyi ti Oun ti là silẹ?

Jesu yoo tun pada wa fun awọn ti n wo ọna fun bibọ̀ Rẹ̀.  Gẹgẹ bi awọn Ọmọ Israẹli ti n wọna fun Aarọni lati ti inu Agọ jade wá, bẹẹ ni a n wọna fun Jesu lati sọkalẹ lati Ọrun, lati mu awọn eniyan Rẹ̀ pada pẹlu Rẹ̀. O ti sọ pe Oun o pada wá fun awọn ti n reti Rẹ̀.

Ki ni itumọ wiwọna fun Jesu?  A ni lati ni idalare nipasẹ Ẹjẹ ti O ta silẹ.  A ni lati ni isọdimimọ́, ki ẹda ẹ̀ṣẹ ajogunba wa le kuro, bakan naa nipa Ẹjẹ Jesu.  Lẹyin naa a ni lati ni ifiwọni Ẹmi Mimọ́. Nigba ti Jesu lọ si Ọrun O ṣeleri fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe Oun o rán Olutunu, Ẹmi Mimọ́, lati jẹ́ Amọna wa “si ọ̀na otitọ gbogbo.”  Jesu paṣẹ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe ki wọn jokoo “titi a o fi fi agbara” wọ̀ wọn, “lati oke ọrun wa”  (Luku 24:49).  Aṣẹ yii wà fun wa lonii, pẹlu.  A ni lati rìn ninu gbogbo imọlẹ Ọrọ Ọlọrun ti o mọlẹ si ọna wa, ki a ba le ṣe tan lati pade Jesu nigba ti O ba de.

**Ewurẹ Idasilẹlọ**

Ewurẹ meji ni wọn n fi rubọ ni Ọjọ Etutu.  A kà pe wọn maa n pa ọkan, wọn a si mu ẹjẹ rẹ̀ lọ sinu Ibi Mimọ́ Julọ.  Ekeji ni wọn n pe ni ewurẹ idasilẹlọ (o jẹ alaaru ẹbi). Nigba ti ẹni kan ba ru ẹbi ti i ṣe ti ẹlomiran ni a maa n pe ni ewurẹ idasilẹlọ.  Eyi ni nnkan ti ewurẹ idasilẹlọ akọkọ ṣe.  O duro lai mira nigba ti Aarọni ba gbé ọwọ rẹ̀ lé ori ewurẹ naa ti o si jẹwọ gbogbo ẹ̀ṣẹ Israẹli le e lori.  Lẹyin eyi, ewurẹ naa tẹle ọkunrin kan ti o mu un lọ sinu aginju nibi ti o rin sọnu si.  Kò si ẹni ti o tun n ri ewurẹ naa mọ́.  Eyi jẹ́ apẹẹrẹ Jesu, ti O yọọda lati wá si ayé, ti O gbé ẹ̀ṣẹ wa ru ara Rẹ̀, ti O si kú lati pa ẹ̀ṣẹ run fun gbogbo ẹni ti yoo ba tọ Ọ wá pẹlu ironupiwada, ti yoo si gbagbọ́.

Bayii ni a ri i pe ni Ọjọ Etutu a ni apẹẹrẹ pipe fun ohun ti Jesu ṣe nigba ti O wá sinu ayé yii  tifẹtifẹ lati ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ ki a ba le ri idariji ati imukuro ẹ̀ṣẹ wa, ki a má si ṣe tun ranti wọn si wa mọ́.

**AWỌN IBEERE**

1. Apẹẹrẹ ki ni Ọjọ Etutu jẹ́?
2. Ta ni n rú ẹbọ ti o si n ṣiṣẹ isin ninu Agọ ni ọjọ yii?
3. Ki ni o le ṣe ni ọjọ yii ti oun kò le ṣe ni ọjọ miiran?
4. Bawo ni o ṣe n mura silẹ ki o to wọ Ibi Mimọ́ Julọ?
5. Ki ni n jẹ ewurẹ idasilẹlọ (alaaru ẹbi)?
6. Ki ni ṣẹlẹ si ewurẹ keji?
7. Bawo ni awọn ewurẹ naa ti jẹ́ apẹẹrẹ Jesu?
8. Bawo ni a ṣe le ni idariji ati imukuro ẹ̀ṣẹ wa?